# “TANI WA NIHA TI OLUWA?”
## Ẹksodu 24:12-18; 31:18; 32:1-35
## ẸKỌ 67 FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: “Iwọ kò gbọdọ li ọlọrun miran\pẹlu mi” (Ẹksodu 20:3).**

**Israẹli Niwaju Oke Sinai**

Ni igba kin-in-ni ti Mose pada lati ori oke pẹlu aṣẹ lati ọdọ Ọlọrun pe ki awọn Ọmọ Israẹli ya ara wọn si mimọ́ fun ọjọ mẹta, lẹyin naa ki wọn súnmọ tosi lati gbọ ọrọ ti Oluwa yoo ba wọn sọ, wọn ti fi tifẹtifẹ gbà lati gbọran si Ọlọrun ninu ohun gbogbo. Ijade wọn lati Egipti jẹ apẹẹrẹ igbala, fifi ohun ayé silẹ. Okun Pupa ti wọn là kọja jẹ apẹẹrẹ iribọmi. Ṣugbọn nnkan miiran wà fun awọn ọmọ Ọlọrun lẹyin ti wọn ba ti ri igbala. Ọlọrun n fẹ ki wọn sunmọ tosi, ki wọn si gbọ aṣẹ Rẹ; ki wọn ba A rìn, ki wọn si gbọran si I ninu ohun gbogbo. Ipejọpọ awọn Ọmọ Israẹli ni Sinai jẹ apẹẹrẹ isọdimimọ; ẹ jẹ ki a ro ohun nlá nlà ti Oluwa i ba ṣe fun wọn, bi o ba ṣe pe wọn sunmọ Ọn ki wọn si ṣe ifẹ Rẹ! Wọn bẹrẹ si ṣe ifẹ Ọlọrun, wọn si wẹ ara wọn mọ lode; ṣugbọn nigba ti wọn gbọ́ aṣẹ Ọlọrun (Deuteronomi 5:22), wọn fa sẹyin: “Nitoripe ara wọn kò le gbà ohun ti o palaṣẹ” (Heberu 12:20).

Ọpọlọpọ eniyan lọjọ oni bẹrẹ ire-ije ti Onigbagbọ́; ṣugbọn nigba ti wọn ba mọ ohun ti o jẹ́ lati gbé igbesi-ayé iwa mimọ niwaju Ọlọrun, wọn a fà sẹyin, Ọlọrun kò si ni inu didun ninu wọn. Imọlẹ ti wọn ni a si pada di okunkun.

**Ofin ti a Kọ sori Okuta**

Ọlọrun n fẹ fun awọn Ọmọ Israẹli ni Ofin Mẹwaa ni ọna ti o jẹ pe wọn kò ni gbagbe wọn tabi ki a pa wọn rẹ́ lọkan wọn. O pe Mose ati Jọṣua lati wá sori oke, O si fi ika Rẹ kọ awọn ofin náà sinu wàlaa okuta. Jọṣua ni yoo di aṣaaju awọn Ọmọ Israẹli lẹyin ikú Mose, nitori naa o ṣe pataki pe ki oun, pẹlu súnmọ Ọlọrun, ki o si gbọ ọrọ Rẹ.

Ogo Oluwa bo ori oke naa fun ọjọ mẹfa. Irú ayọ̀ nla wo ni yoo jẹ fun Mose ati Jọṣua ti wọn ni Ẹmi Ọlọrun ninu ọkàn wọn, ṣugbọn fun awọn Ọmọ Israẹli ti wọn n wò o lati okere o dabi “iná ajonirun.” Awọn eniyan ti kò ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn wọn ko le mọ ohun ti Ẹmi, ẹ̀ru iṣẹ iyanu Ọlọrun a si maa bà wọ́n. Ṣugbọn bawo ni iṣẹ Ẹmi Ọlọrun laaarin awọn Onigbagbọ́ tootọ ti dun mọ wọn to!

Ni ọjọ keje ti Mose ati Jọṣua ti wà lori oke, Ọlọrun bẹrẹ si sọrọ. Mose ti kọ́ lati duro de Oluwa, aarẹ̀ kò si mu un. Ọlọrun ṣe ileri pupọ fun wa, ti o yẹ ki a gbagbọ́, a ko si gbọdọ sọ ireti nù nitori Ọlọrun fi idahun Rẹ falẹ nigba miiran. Ileri ti o tobi ju lọ ni ipadabọ Oluwa wa sinu ayé. O ti fa bibọ Rẹ̀ sẹyin, ṣugbọn awọn ọmọ Rẹ̀ n foju sọna pẹlu ireti nla fun bibọ Rẹ̀, wọn kò si jẹ ṣe iyemeji ọjọ nla náà.

**Biba Ọlọrun Sọrọ**

A ko sọ pe Mose jẹun rárá fun ogoji ọjọ ti o fi wà lori oke. A gbagbọ pe ogo Ọlọrun kun inu rẹ to bẹẹ ti kò ronu nipa ounjẹ ti ara. Nigba ti Ọlọrun ba fi iwuwo adura sinu ọkàn awọn eniyan Rẹ̀ lati gbadura tọkantọkan fun ohun kan, wọn a gbagbe ounjẹ wọn nigba miiran. Nigba ti ẹni kan bá gbadura tọkantọkan yoo wa ni iṣọkan pẹlu Oluwa, yoo si mu un gbagbe gbogbo ohun ti o yi i ká fun iwọn igba diẹ. Bi eniyan ti n fi ara rẹ rubọ si i ni yoo rọrun fun un to lati wà ni iru iṣọkan bayii pẹlu Ọlọrun. Bi a ba ti n gbadura to, ni a o maa fẹ lati gbadura si i. Bi ẹni kan ba ti ni iru iṣọkan bẹẹ pẹlu Olugbala ri, yoo mọ pe ohun kan ti sọnu ni igbesi aye oun nigba ti o ba ṣe alainaani adura. Nigba ti o ba fi ainaani sọ ifẹ ati gbadura nù, yoo mu Ẹmi Ọlọrun binu; bi o ba si n ba eyi lọ bẹẹ lai pẹ yoo dabi ibi gbigbẹ ninu aṣálẹ̀, ti i maa wa ni iyangbẹ ilẹ ninu aginju (Jeremiah 17:6).

Mose fi awọn eniyan naa si abẹ itọju Aarọni ati Huri nigba ti o lọ ba Ọlọrun sọ̀rọ. Wọn yoo maa dahùn ibeere awọn eniyan naa, wọn yoo si maa ṣe ilaja laaarin wọn.

**Awọn Eniyan Naa fẹ Ọlọrun Miiran**

Njẹ o le foju inu wò ohun ti o jẹ iṣoro kin-in-ni? Wọn fẹ ọlọrun miiran. Ofin kin-in-ni ti Ọlọrun ti fi fun wọn ni pe wọn kò gbọdọ ni ọlọrun miiran pẹlu Oun, wọn kò si gbọdọ yá ere kan lati fori balẹ fun. Nisisiyii wọn ti n ṣe aigbọran si Ọrọ Rẹ.

Iwe Mimọ́ sọ fun ni pe awọn eniyan naa sin Oluwa wọn si fori balẹ fun ẹgbọrọ maluu. Ogo Ọlọrun ti wọn ti ri lori oke ti n rú eefin ti dinku lọkan wọn, ko si ju ẹgbọrọ maluu wura lọ loju wọn mọ. Wọn wi pe “Israẹli, wọnyi li oriṣa rẹ, ti o mú ọ gòke lati ilẹ Egipti wá.”

Ẹ jẹ ki a wo diẹ ninu awọn ohun ti Ọlọrun ti ṣe fun wọn laaarin oṣu mẹrin sẹyin. Lẹyin ti Ọlọrun ti fi ajakalẹ-arun buburu, eyi ti awọn alalupayida kò lagbara lati mu kuro tabi ki wọn ṣe iru rẹ, kọlu awọn ara Egipti, O ti pin Okun Pupa niya ki awọn Ọmọ Israẹli ba le rin kọja lori ilẹ gbigbẹ. Nigba ti awọn Amaleki gbogun ti Israẹli, Ọlọrun fun wọn ni iṣẹgun nla nipa Jọṣua ti o ṣaaju ogun naa ati Mose ti o wà lori oke pẹlu Aarọni on Huri ti wọn n bẹbẹ lọdọ Oluwa. Nigba ti ebi n pa wọn, Ọlọrun fun wọn ni aparo ati manna lati jẹ, (sibẹ wọn n jẹ manna ti Ọlọrun n fun wọn lojoojumọ). A mú omi jade fun wọn lati inu apata gbigbẹ nigba ti oungbẹ n gbẹ wọn. Gbogbo nnkan

wọnyii ni Israẹli mọ̀, sibẹ wọn le sọ ninu ifọju ọkàn wọn pe, “Israẹli, wọnyi li orișa rẹ ti o mú ọ gòke lati ilẹ Egipti wá.”

A ranti pe awọn ara Egipti a maa sin maluu; ṣugbọn nigba ti idajọ Ọlọrun wá sori ilẹ wọn, awọn maluu wọnyii kú. Kò si ọ̀kan ninu awọn orișa wọn ti o lagbara lati ràn wọn lọwọ. O yẹ ki awọn Ọmọ Israẹli ti kọ́ ẹkọ ninu eyi, ti kò yẹ ki wọn yara gbagbe.

Iru iwa aimoore ati ẹmi aigbagbọ bayii kò yé ni, ṣugbọn ọpọ awọn eniyan lọjọ oni ni oju wọn fọ́ si iṣẹ iyanu ti Ihinrere Ọlọrun! O n șișẹ iyanu nipa sisọ ẹlẹṣẹ di eniyan mimọ́, nipa wiwo alaisan sàn, ati ni aimoye ọna miiran ti O n fi ara Rẹ̀ hàn. Sibẹ ọpọ awọn eniyan kuna lati ri ọtitọ ti ó wà ninu ẹsin Bibeli.

**Ibinu Ododo Ọlọrun**

Inú Ọlọrun kò dun si awọn eniyan wọnyii (n jẹ Ọlọrun ko jare?) ti O fi mura lati pa gbogbo orilẹ-ede naa run. O ṣeleri lati gbe orilẹ-ede miiran dide lati inu iran Mose, nitori inu Rẹ̀ dun si ọkàn tutu ati igbọran Mose.

Ṣugbọn Mose kò wá ọlá ati ọrọ̀ fun ara rẹ. Inu oun paapaa ko dùn si ohun ti awọn ọmọlẹyin rẹ ṣe, ṣugbọn o fẹ ki orukọ Ọlọrun di ayinlogo. Bi gbogbo awọn Ọmọ Israẹli ba kú nisisiyii awọn ara Egipti le wi pe Ọlọrun kò ni agbara lati mu wọn lọ si Ilẹ Ileri, nitori idi eyi ni o si ṣe jẹ ki wọn parun ni aginju. Mose fẹ ki gbogbo agbaye mọ agbara Ọlọrun, nitori naa o bẹ Ọlọrun lati dariji awọn Ọmọ Israẹli. Irú ẹni iyanu wo ni Mose jẹ́ lati fẹran awọn ẹlẹṣẹ wọnyii to bẹẹ ti yoo fi bẹ Ọlọrun lati dá ẹmi wọn si!

Jesu ṣe ju eyi paapaa lọ fun wa. Iwe Mimọ́ sọ fun wa pe Jesu kú fun awọn ọta Rẹ̀. Ọlọrun ko le wo ẹṣẹ ni ọna miiran ju lati binu si i lọ, ṣugbọn Jesu ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ ki Ẹjẹ naa ba le bo ẹ̀ṣẹ wa mọlẹ, ki o si le pa a mọ kuro loju Ọlọrun. Jesu ko kú nitori ẹ̀ṣẹ Oun tikara Rẹ̀ -- Oun ko tilẹ dá ẹ̀ṣẹ kan rí. O la gbogbo ijiya Rẹ̀ kọja nitori ẹ̀ṣẹ ti rẹ, ati ti emi.

**Agbara Adura**

Ro iru agbara ti Mose ni ninu adura rẹ̀ si Ọlọrun. O rán Ọlọrun leti ileri ti O ti ṣe fun Abrahamu, Isaaki ati Jakọbu, pe iru ọmọ wọn ni yoo jogun ilẹ Kenaani. Mose bẹ Oluwa lati ranti awọn ileri wọnyii ki O si ṣaanu fun Israẹli ti o ti dẹṣẹ.

Nigba ti a ba wá sọdọ Ọlọrun, a ni ẹtọ lati rán An leti awọn ileri Rẹ̀. Bi a ba ṣaapọn lati ka Ọrọ Ọlọrun tọkantọkan awa yoo mọ ohun ti awọn ileri wọnyii jẹ, a si le gbadura pẹlu igbagbọ nitori a mọ̀ pe Oun yoo mu Ọrọ Rẹ̀ ṣẹ. Njẹ ko ya ni lẹnu pe awa ẹni irẹlẹ ẹda ọwọ Ọlọrun le gbadura si I ni ọna ti yoo mu idahun wá fun ire wa?

**A fi Ẹṣẹ Hàn**

Ọlọrun sọ fun Mose ohun ti awọn eniyan naa n ṣe nigba ti ko si laaarin wọn -- ẹṣẹ ti o buru pupọ ti wọn n dá. Ọlọrun maa n jẹ ki awọn alufaa Rẹ̀ mọ̀ nigba ti ẹ̀ṣẹ ba wọ inu ijọ wọn. O mọ ohun gbogbo; ko si ẹṣẹ ti o pamọ loju Ọlọrun; ko si ni ṣe ẹnikẹni ni ire lati maa gbadura bi oun ko ba fẹ kọ ẹ̀ṣẹ rẹ̀ silẹ. “Ẹniti o bo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ mọlẹ kì yio ṣe rere: ṣugbọn ẹnikẹni ti o jẹwọ ti o si kọ̀ ọ silẹ yio ri ãnu” (Owe 28:13).

Nigba ti Mose ati Jọṣua sọkalẹ lati ori oke, wọn gbọ́ ariwo orin bi awọn eniyan naa ti n jó yí ẹgbọrọ maluu wura naa ká. Nitori wọn ṣe aibu ọla fun Ọlọrun, inu bi Mose si awọn Ọmọ Israẹli to bẹẹ ti o fi sọ awọn walaa okuta ti Ọlọrun kọ Ofin Mẹwaa si silẹ -- wọn si fọ́, gẹgẹ bi Israẹli paapaa ti rú ofin nipa iṣẹ wọn.

Mose mu ẹgbọrọ maluu wura naa, o si lọọ di ẹ̀tù. O ku eeru naa soju omi, o si mu ki awọn eniyan naa mu un. Ẹgbọrọ maluu yii kò tilẹ ni agbara lati gbeja ara rẹ̀, bawo ni yoo si ti ṣe le ni agbara lati mu awọn Ọmọ Israẹli jade kuro ni Egipti.

Aarọni gbiyanju lati dá ara rẹ lare nipa ipa ti rẹ ninu ẹ̀ṣẹ yii. O wi pe awọn eniyan ni wọn fun oun ni wura; lẹyin ti oun si ti sọ ọ sinu iná lati yọ́, ẹgbọrọ maluu si jade wá. Ṣugbọn eyi ki i ṣe otitọ, nitori Iwe Mimọ́ wi pe o “si fi ohun-ọnà fifin ṣe e.”

Mose woye boya awọn ẹni rere le kù sibẹ ninu awọn eniyan rẹ. O sọkalẹ lati ori oke lati fun wọn ni ibukun Ọlọrun, ṣugbọn wọn fihàn pe wọn ko lẹtọọ si i, nitori bẹẹ a yí ibukun yii pada si idajọ.

Mose duro niwaju awọn eniyan naa, o si beere lọwọ wọn bi ẹnikẹni ba wa ti yoo mu iduro fun Ọlọrun. Gbogbo awọn ọmọ Lefi jade wá si iha ti Oluwa. Awọn wọnyii ko pọ pupọ ti a ba fi wé ogunlọgọ awọn eniyan ti a fi ibeere yii siwaju rẹ. Ọlọrun lò wọn lati jẹ awọn ẹlẹṣẹ wọnyii niya, ẹgbẹẹdogun (3,000) eniyan si kú lọjọ naa, nipa idà awọn ọmọ Lefi.

Ta ni wà nihà ti Oluwa lonii? Ki i ṣe ọpọ eniyan ni wọn n fẹ mu iduro wọn lati wà niha onirẹlẹ Ara Nasarẹti; ki i ṣe ọpọ eniyan ni wọn fẹ jiya diẹ nihin ki wọn ba le jọba pẹlu Kristi nigba ti o ba de ninu ogo Rẹ̀. Awọn eniyan i ba le mọ̀ bi iye ainipẹkun ti ṣe pataki to ju akoko diẹ ti a ni i lò ninu ayé yii, wọn i ba sare lọ si ẹsẹ̀ agbelebu, ki wọn si ronupiwada, ki wọn si kigbe pe Olugbala fun aanu.

Mose pada tọ Ọlọrun lọ, o si bẹbẹ pe ki o dari ẹ̀ṣẹ awọn eniyan wọnyii jì wọ́n. O gba pe wọn ti dẹṣẹ nlá, ṣugbọn o fẹ ki aanu Ọlọrun bo o mọlẹ. Bi Ọlọrun kò ba ni dariji awọn eniyan naa, Mose fẹ ki a mu ipa ti oun kuro ninu

Iwe Iye. Ṣugbọn eyi ki i ṣe ọna Ọlọrun. O wi pe "Ẹnikẹni ti o ṣẹ̀ mi, on li emi o parẹ́ kuro ninu iwé mi." Mose kò dẹṣẹ; ki ni ṣe ti yoo fi jiya?

Mose ṣe etutu (eyi ti i ṣe ẹbọ nipa tita ẹjẹ silẹ) fun ẹ̀ṣẹ awọn eniyan naa: Ọlọrun ṣaanu fun wọn. O sọ fun Mose lati tẹsiwaju, ki o si mu awọn eniyan naa lọ si Ilẹ Ileri. Ṣugbọn Ọlọrun rán ajakalẹ-arun si wọn nitori wọn ti ṣe ẹgbọrọ maluu wura, wọn si ti sin in.

**AWỌN IBEERE**

1. Nibo ni agọ́ awọn Ọmọ Israẹli wà, ni akoko ẹkọ wa yii?
2. Ki ni ṣe ti ẹ̀rù Ọlọrun fi ba awọn eniyan wọnyii?
3. Ta ni bá Mose lọ sori oke? Ki ni ṣe?
4. Ki ni ohun ti awọn eniyan naa ṣe nigba ti Mose ti lọ?
5. Bawo ni a ṣe jẹ wọn niya nitori ẹ̀ṣẹ wọn?
6. Ki ni ṣe ti Ọlọrun ṣaanu fun wọn?
7. Awọn wo ni wọn jade wá siha ti Oluwa?